# EKO NIPA KOKORO HIV.

HIV ni kokoro eyi to n fa aarun AIDS, aarun yi a ma gbogun ti awon olopa ara wa.O ti to milionu meji din logbon eniyan ti arun yi ti gba emi won ni agbaye. Kokoro HIV yi digbo lu awon olopa ara won to bee ge ti oriririsi arun bere si wo ago ara won.

Odun 1981 ni akoko se ibapade arun AIDS. Ni odun 1983 ni a ri daju wipe kokoro HIV ni o n fa arun yi. Leyin ogun odun ti a ti ni awon imo wonyi, a ko i ti ri abere ajesara tabi oogun eyi to le wo arun yi san patapata.Sugbon awon oogun ti wa eyi to le mu ki emi awon ti o ni arun yi gun die si.
A ti fi han wipe ninu awon eya obo kan ni kokoro HIV ti je yo. O se se wipe ni igba ti awon eniyan n pa awon eranko wonyi lati je ni awon adugbo kan ni ile Afirika ni arun yi koja si ara awon eniyan bee. A le so wipe arun yi bere si ni ja ni ikoko ki o to wa di ajakale eyi to n sele loni.

Kokoro to n fa arun yi bere si ni tan kale gidigidi ni ile Afirika. Lara awon ohun to ran ajakale yi lowo ni ile Afirika ni kiko ti awon eniyan bere si ni ko kuro ni awon igberiko lo si awon ilu nla- eyi tu opo awon idele ka. Ogun ati iwa eleya meya pelu ran kokoro yi lowo lati ma gbile si. Iwadi si ti fi han wipe eya kokoro HIV ti a maa n ba pade lara awon inaki je idapo iru kokoro yi ti a maa n ri lara awon eya obo meji miran—idi ni wipe awon naki a maa pa awon eya obo wonyi je.

AWON OLOPA ARA:

Kokoro HIV je kokoro to buru pupo. Kokoro yi a maa je wo inu awon eya ara eniyan to be gee ti o soro gidi lati mu won kuro.

Kokoro HIV a si maa pa ara da ni kia kia, bakan na kokro yi maa n gbile si ni werewere ninu ara eniyan.

Apo ti o yi kokoro HIV ka fi ara jo apo ti o yi awon eya ara eniyan ka, to bee ti o soro fun awon olopa ara wa lati da awon kokoro yi mo.

O se Pataki lati ni imo nipa bi awon olopa ara wa se n sise ki a baa le ni imo to jinle nipa bi kokoro HIV se n ba ara wa ja.

Awon olopa ara a maa da aabo bo ara wa ki awon kokoro ti o n fa arun ma le ri aye wole. Awon olopa ara yi a maa sise ni orisirisi ona lati gbogun ti awon kokoro to n fa arun si inu ara wa. Omije oju, ikun imu wa, ito enu wa, ati awon epo to n sun jade ni ara wa ni ise Pataki lati se lati gbogun ti awon kokoro ti o maa n fa arun wa si ara wa. Bakan naa, a tun ri awon eya kan ninu eje eyi ti o maa n gbe awon kokoro buburu mi patapata ki won ma ba le ba ara wa je.

A tun ri awon eya miran eyi ti o maa n se akoso bi awon olopa ara wa se n se ise. Awon eya wonyi a maa kaakiri gbogbo ara wa, won le gbe awon kokoro buburu mi, won si maa n ran awon olopa ara wa lowo ki won ma baa le doju ija ko ara wa ni akoko ti won ba n gbogun ti awon kokoro buburu.

Ni kete ti awon kokoro buburu ba ti wo inu ara wa, ni awon olopa ara wonyi a bere si gbogun ti won. Ninu awon olopa ara wonyi ni ati ri awon ti o le pa awon kokoro wonyi run lesekese. Awon miran ninu awon olopa ara wonyi ni ise Pataki lati maa ran gbogbo awon eya ti o ku lowo lati se ise won deede. Awon eya oluranlowo yi gan ni kokoro HIV maa n doju ija ko lati bori awon olopa ara wa, eyi ti o maa n yori si arun AIDS ti a ti n so nipa re.

Awon eya oluranlowo wonyi ni orisi ise ti won n se ninu ara. Won a maa ran ara wa lowo lati pese awon eroja kan eyi ti o le mu ki awon kokoro buburu di

Po bi koko ki ara wa ba le tete gbogun ti won. Awon eroja miran a si maa lu iho si ara awon kokoro buburu yi ki won ba le ku patapata.

A tun ni awon eya kan eyi ti o maa n ranti awon kokoro buburu ti o ti wo inu ara wa ri. Ti awon kokoro bayi ba tun wo ara wa ni awon igba miran, logan ni ara wa maa dide ija si won, nitori wipe ara wa ti ni iranti won. Idi ni yi ti abere ajesara maa n daabo bo wa lowo awon arun.

Awon eya ara eyi ti a pe ni oluranlowo wonyi ni ise Pataki lati se ki awon eya ara to ku le se ise won de oju osuwon lati gbogun ti awon kokoro buburu eyi ti o le se ibaje ninu ara wa, awon gan ni alakoso gbogbo awon olopa ara wa.

Ni awon akoko miran, awon kokoro ti o maa n fa aisan maa n sa ipa lati wo inu ara wa. Ni kete ti won ba ti wo inu ara wa, awon iyipada kan a maa sele ti o maa n fun awon olopa ara laaye lati gbogun ti awon kokoro bee.

AWON ONA TI A FI LE KO ARUN HIV:

Kokoro HIV ko ni agbara lati koja sinu ara wa, a fi ti a ba ni ogbe lara. A le ko kokoro HIV ti omi ara ba dapo mo ara won. A ko le ko kokoro yi lati inu igbe, nipa iko wiwu, nipa awon kokoro ti o le ge eniyan je, tabi nipa biba eniyan gbe ile po. Ona meta ni kokoro yi maa n gba wo inu ara eniyan- nipa iba lopo, nipa idapo eje, ati lati ara iya si omo. Ibalopo ni ona ti a fi le tete ko arun yi kia kia.

Ida metala si marundinlogoji awon aboyun to ni kokoro HIV lara ni o maa ko arun yi ran awon omo won yala lati inu oyun tabi ni akoko ikunle. A ti fi han wipe kokoro HIV po gidi ninu omi omu pelu. Awon to n sise ni ile iwosan le ko arun yi ti abere alaisan HIV ba gun won lara. Bi o ti le je wipe kokoro HIV wopo gidi ninu ito enu, a ko le ko arun yi nipa fifi enu ko ara eni lenu.

ISE KOKORO HIV:

Ni kete ti kokoro HIV ba ti wo inu ara eniyan, awon olopa ara wa maa bere si ni gbogun ti kokoro yi, sugbon agbara awon olopa ara ko le ka kokoro yi lati pa won run. Kokoro HIV maa n doju ija ko awon eya oluranlowo ti a ti so oro won tele, won a bere si ni pa awon eya yi run. Nitori idi yi ago ara eniyan ko ni ri agabara lati doju ija ko awon aarun. Eyi gaa ni o maa n fa arun AIDS wa.

O se se ki a ri odun mejo si mewa ki arun yi to da eniyan wole, nitori werewere ni arun yi maa n gbile ninu ago ara eniyan. Nitori idi yi ni a se n ri opo isoro lati le tete se ayewo tabi lati ka apa arun buburu yi. Ni awon akoko miran, arun yi a maa tete gbile ninu ara awon eniyan miran ,to be ti arun yi le da eniyan wole ni kia kia .

Die die ni arun HIV maa n gbile ninu ara eniyan. Ni akoko , o soro gidi lati mo eni ti o ni arun yi lara, a fi ti a ba se ayewo eje fun iru eniyan bee. Ni awon igba miran, efori, ara riro, ati bebe lo le fi ara han ninu awon to ni arun yi. Awon apeere won yi ko fi dani loju wipe arun HIV ti wo ara eniyan nitori wipe a le ri iru apeere bawon yi ninu awon aisan miran pelu.

Kokoro HIV yi maa n digbo lu awon olopa ara eniyan die die titi yi o fi doju won bole patapata. Awon arun bi igbe gbuuru, ati awon arun jejere a bere si ni fi ara han ninu ara eniyan. Opo awon arun ti o maa n yo oju si awon to ni arun HIV je arun ti ko ye ki o le da eniyan wole rara. Arun wonyi si le se iku pa awon to ni arun AIDS.
Awon iru eniyan kan wa ti arun yi ko le ri aye ninu ago ara won. Idi ni wipe ara awon eniyan bee ko ni awon eroja ti kokoro HIV maa n lo lati gbile ninu ara. Awon isori eniyan miran ni awon ti kokoro yi le wo ara won , sugbon ti won ko ni tesiwaju lati ni arunn AIDS. Awon eniyan bayi le gbe kokoro HIV pamo sara fun nkan bi odun mejidinlogun.

O to iru marun kokoro HIV ti a ti mo bayi. Awon iru kan wopo ni iha ariwa ile Amerika, ti awon kan si wopo ni awon iha ile Afirika to sun mo apa Sahara.
Kokoro HIV maa n yara lati gbile ninu ara, a si maa pa ara da kia kia. Idi ni yi ti o fi soro lati toju arun AIDS, ati lati ri abere ajesara si arun naa.
Kokoro HIV tete maa n parada to bee ti awon oogun ti a maa n lo ko ni ka apa re mo.

Translated into Yoruba Language by:
Dr. Adeoti, Abolaji.
Pretoria, South Africa.
13th/NOV/2007.